**EKO KINNI**

**JESU EBUN OFE IGBALA**

**Dida eniyann ni aworan Olorun.**

**Olorun je emi, o si wa ni metalokan (Baba, Omo ati Emi Mimo)**

Ni iberepepe, Olorun so wipe e je kii a da eniyan nii aworan ara wa.

A da eniyan pelu nnkan meta pato. (Iseda meta ti Eniyan) Tesalonika 1, 5:23

**Emi Eniyan:** eyi ni eda inu eniyan ti o ni ibasepo pelu Olorun. Abala eniyan ti je akojopo eri okan, igbagbo ireti, ife ati iwuwasi.

**Okan eniya**n: eyi ni ibujoko bi a se je, igbeaye inu eniyan ti je akojopo okan, ife-okan,oju inu, ero okan, ife okan, imoose ati ala.

**Ara eniyan:** eyi ni eya ti ita enitan ti o se fi oju ri fun gbogbo eniyan. Eyi nii apo ti a ko emi ati okan erupe wa si.

Eto bi olorun se seda Adamu ati Efa ni iseda meta:

1. Emi eniyan ko ipo kinni.
2. Okan eniyan ko ipo keji.
3. Ara eniyan ko ipo keta.

Ni ona miiran, emi eniyan lo n se akoso okan ti o si maa n fi ifiranse si ara ti yoo se kokari ase na.

Apere kan ni Oko, olori ile ti o nii iyawo ti o si gba omo odo fun iyawo re.

Nigba ti oko na ba fe ki won pese irufe ounje kan fun. Oko yoo pe iyawo re latii so fun, irufe ounje ti o fe ko se. Iyawo yoo wa so iru ounje na fun omo odo ti yoo se ounje na.

Oko (Emi) pa ase fun iyawo.

Iyawo (Okan) ti ase naa si omo odo.

Omo odo (Ara) mu ase na wa si imuse.

**Ese Adamu ati Efa.**

Adamu ati Efa ni Okunrin ati Obinrin akoko ti a da, satani tann won je ninu ogba edeni si inu aigboran. Genesisi 3:2-6. Gbogbo aigboran je iwa ese. Gbogbo ese ni o ja si iku. Roomu 6:23

Genesisi 3:3 iwo ko gbodo je tabi fowokan ki o ma baa ku.

Genesisi 3:4 Ejo si so pe iwo koo le ku.

Ibeere: leyin ti won je eso, Nje adamu ati efa ku?

Ibeere: kilo fa ti o fi je wipe, pelu gbogbo ese ti awon eniyan n da, won si n be laaye?

Se enikeni mo iru iku ti awon eniyan n ku nigba ti won ba da ese?

Idahun: iku ti emi eyi ti o mu ki emi eniyan yapa pelu Olorun.

Ipin meta awon etan satani. Genesisi 3:6

1. Ifekufe ti oju.
2. Ifekufe ti ara
3. Igberaga ti isemi.

Ifekufe ti oju: Obinrin na ri igi naa pe o dara ni oju, ohun gbogbo ti o se itewogba si oju ti ko se telorun (Oniwasu 1:8) ni eka idanwo yii, satani ma n lo ifanimora ti ita (yala ohun ti o dara ti a nife si bii ile tabi Oko, tabi ohun ti ko dara ti a fe bii iyawo alabagbepo wa) lati mu ojukokoro wa.

Ifekufe ti Ara: Obinrin naa wa rii bii igi ti o nifesi (genesisi 3:6) eyi nii ohun gbogo ti o se itewogba si ara ati si iyalenu ti ara. Satani maa n lo ife to lagbara fun nnkan ti ara lati ko eniyan leru. O wa ma ro bi aye re yoo se dara to pelu re.  Iseju ti ife afoju yii ba ti bori re, ati subu sinu ese yoo rorun.

Igberaga ti Emi: lati mu eniyan gbon, eyi ni ohungbogbo to se itewogba si irera, ikapasoke atii igberaga ninu wa. Ninu idanwo yii satani a maa lo isasaroo lori awon ohun ti a ti da tabi ti a kojo (bi apere, bi ase gbajumo to, iwe, aseyori, imoye) ni kete ti eniyan ba ti subu sinu pakute igberaga ti emi, satani ti bori ogun.

Ibeere:Nje enikeni mo atunse si bibori idanwo?

Idahun: Atunse naa ni lati sare to olorun lo ninu adura (gba mi lowo ibi). ki o daruko ibi naa fun Olorun. Pelu iranlowo olorun, yoo da omi tutu si ori ina idanwo lati se ibi naa, iwo yoo si di ominira.

**Iku ati Ese bere lori Adamu ati Efa si ori gbogbo iseda.**

Eni rere kan ko si, gbogbo wa ni elese ni aye yii, Iku si joba lori gbogbo wa lati ori Adamu de Moose, koda lori awon ti ko da ese leyin…….. ese adamu, eni ti o je aworan anito n bo. Roomu 5: 12-14

Ese ati isubu Adamu yi Ipin meta eda eniyan pada.

Ara eniyan n se akoso okan eniyan, emi si ku tabi dake roro.

**Jesu, ebun ofe ti igbala.**

Nitori Oloru fe araye to bee ge to fi omo bibi re kan soso fun wa, pe enikeni to ba gbagbo ninu re ki yoo segbe, sugbon ni iye ainipekun. (Johanu 3:16)

Sugbon ebum olorun ni iye ainipekun nipase Jesu kristi oluwa wa (Roomu 6:23).

**Bi a se le gba ebun Jesu.**

Ti iwo ba fi enu re jewo ti o si gbagbo ninu okan re pe a ji jesu dide ninu oku, a o gba o la.nitori eniyan gbagbo ninu okan si ododo ati pelu enu wa ni a fi n jewo si igbala (roomu 10:9-10)

Gbigba Jesu yoo mu o di ebi olorun.

**Awon anfaani didi ebi olorun po sugbon die ninu e niwonyii:**

Gegebi omo olorun, a je alaabapin ninu oro ebi naa: Emi mimo ni ohun ini to ga ju , eni ti o n to wa sona ti o si n tu wa ninu ni gbogbo nnkan. A tun ni anfaani si aabo, agbara, ife ati ibukun olorun.

**Ibeere tabi afikun lori oro iwaasu lati enu awon ara ijo.**

**Ipe si ironupiwada:** ti mo ba maa fiwe pe o lati gba jesu sinu aye re loni, nje oni maa je ojo ti iwo o gba ebun ofe ti igbala yii ki a si tu o sile ninu ide satani lati di ebi olorun?

**NI KI OLUKULUKU DI OJU WON KI WON SI MAA BERE PE KI OLORUN KO FI OWO TO OKAN WON.**

Ti o ba maa nife lati gba jesu sinu aye re, jowo na owo re soke ki o si wa si iwaju lati gba adura.

**Adura igbala**

Jesu oluwa, mo jewo wipe elese ni mi,momko gbogbo ese mi sile mo si bebe pe ki e darijji mi, wemi pelu eje re ki o si wa sinu aye mi lati gba mi. Mo gba o gege bu oluwa ati olugbala mi. Mo gbagbo ninu okan mi pe o ku o si jinde kuro ninu oku lati gba mi. Ose ti o gba mi oluwa, ni oruko jesu, Amin.

Leyin adura, beere pe ki won ko oruko won, number ero ibanisoro won ati ijuwe ile won ki o si ni ki won pada si ori ijoko won. Nigba ti won ba ti joko tan, fun won ni oro imoran igbeyin.

**Ko ara re ni ijanu lojoojumo, gbe agbelebu re ki o si ma to mi leyin (Marku 8:34)**

Gbigba Jesu sinu aye re je ibere irin ajo. Eyi maa mu ki emi omo eniyan to ti ku ko sise pada, yoo si mu wa si abe idari emi mimo. Bi a se n so eso si ti kiko ti eni emi mimobere lati ma se imubosipo agbara ti emi ti o lo si ti iye. Eyi je ilana si igbesi aye ojoojumo. Bi o ba si ti n se eyii lojoojumo, emi eniyan yoo bere si ni gba agbara pada lati bori eran ara ati lati mu wa si iteriba pipe.ti emi eniyan. Nitorinaa, emi yoo si gba akoso okan ati ara gegebi olorun bi olorun se seto re.

**Adura Ipari:**